**Wanted**

Two Young Editors who can Manage a Yoruba News paper and collect Advertisements

Apply in persons:-
To
IROHIN IMOLE
16 Bamgbose St.
Lagos.

# IROHIN IMỌLE

MOTTO: IMỌLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

**GBANJO O!!**

Euyin Alagbede, (Gold smith) ati Fadaka (Silver smith) E sore wa ra Opoku-Oyoku "SILVER" E here lodo :-

**Korede Store
108, Evans Street
Lagos. Phone: 23336**

VOL. V No. 207 MONDAY MAY 22 — MAY 26 1961 KỌBỌ KAN (1d)

# Kilo p'Agan Omi Ajalolo, Olopa hu oku Omo ile eko ti nwon ti sin jade

EKO:- ORỌ KO DUN NI OKO LANIYAN LỌNA IKORODU NIGBATI AWỌN OL PA LỌ HU OKU ỌMỌDEBINRIN KAN TI O NLỌ SILEWE IDEAL GIRL SCHOOL,YABA TI ORUKỌ RẸ NJẸ RONKẸ EPẸGA, AWỌN ỌLỌPA GBE OKU ỌMỌ ỌBINRINNA LỌ SILE ALAISAN FUN AYẸW LATI MỌ IKU TO PA AGAN. GẸRẸ TI AWỌN ỌLỌPA GBE OKU ỌMỌ NA LỌ TAN, NI NWỌN RANṢẸ PE BABA TO BI ỌMỌ NA, TI O NGBE SURU LLERELATI WADI ỌRỌ LẸNU RẸ, NWỌN BERE ỌWỌ BABA ỌMỌ NA WIPE NIBO NI ỌMỌ RẸ TI ONJẸ RONKẸ GBE WA?

AWỌN ỌLỌPA SE AKIYESI WIPE, SINSIN TI NWỌN SIN OKU ỌMỌ NA MU AREKEREKE DANI, AWỌN ỌLỌPA TI O N T U N PẸNPẸN BERE WIPE, AWỌN FẸ RI IWE TI O GBA KI O LỌ SIN OKU ỌMỌ NA.

Alaṣẹ awọn Ijọba ti o nṣe iwe awọn oku sọ w pe on ti yẹ gbogbo inu iwe wo, on ko ri orukọ Ronkẹ nibẹ, on ro pe nwọn ko gba iwe fun ki nwọn to lọ ṣinku tẹ.

Alufa D. A. Epẹga ti iṣe baba ọmọ ti o ku na, gba

WỌ IYOKU NI OJU EWE KEFA

## MOGBAYI BABY MIXTURE
OLURANLỌWỌ FUN AWỌN ABIYAMỌ




MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ ogun pa taki ta ṣe ni aṣepe fun awọn Ọmọde, ati nlo ogun yi fun ọpọlọpọ ọdun sẹhin pelu idaniloju fun Awọn iṣẹ ribi ribi ti o ti ọṣe.

MOGBAYI BABY MIXTUREjẹ egbogi to, dara fun igbona ikọ, otutu, A i p e r i, Osi inu Ọmọde, jẹdi jẹdi, kokoro ori ọ tu ọ d.e. O dara fun ọmọde ti ko tete rin ati fun awọn aisan miran bẹbẹ lọ. O nmu ki ọmọde ma nsun fọnfọn, o nmu ki ehin hihu jẹ irọ run fun awọn ọmọde osi njẹki awọn ọmọde tobi, osi nmu wọn dan ni awọ. Euyin Abiyamọ, eku afojuba egbogi yi. Aran yin leti pe MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ egbogi ti ko ṣe mani fun awọn ọmọde. I r a f a r a lewu pupo, tete lọ ra tirẹ ni ile itaja Egbogi towa ni Adugbo rẹ.

Igo kekere re jẹ 2/6d Igo nla jẹ 4/6d

**LILO RE:- Sibi kekere lemeta lojumo**

*Wholesale Distributors*

**A. K. KARIMU ANJOLA & BROTHERS**

6, Balogun Street. West Lagos Nigeria Phone 22515

34, Docemo Street Lagos Phone 24247

## Awon Alejo nla merin de lati ile Amerika

Awọn ọjọgbọn mẹrin kan ba ọkọ Ofurufu gunlẹ si ilu Eko lati wa ṣe alaye ọrọ ye awa enia Dudu ati Ijọba wa fun ilọsiwaju ilẹ wa fun ọdun marun.



Asiwaju awọn Alejo na ni Professor Arnold Rivkin. Alabojuto owo ati Oluwadi Oṣelu nilu Mossachusets sọ fun awọn oniwe Irohin pe, bi bẹ wo ti nwọn wa bẹ wa wo jẹ nipa iṣẹ ti Ọgbẹni Kenedy ran wọn.

Iṣẹ ti o ran wọn na ni nipa iranlowọ ti Amẹrika le ṣe ni iranlọwọ fun ilẹ ajeji, ti o ṣe idagba soke. Iwonyi ni oruko awọn Alejo na: Arnold Rivkin, Wilson Schmidt, Ọgbẹni Anthony Geber ati Lawrence Portter.

# IWE SI OLOTU

## IMỌNRAN FUN GBOGBO ỌMỌ AJASSẸPO, Apa 1.

Lati Ọwọ:- Aliu Akanbi, Ọmọ Aroworọwọn

Olotu jọwọ gbami laye lati ba awọn Ọmọ ibilẹ Ajassẹpo ti iṣe ọmọ Ilu mi sọrọ kekere yi. Akọko ninu ọrọ mi ni wipe, ki gbogbo ẹnyin ọmọ Ajassẹpo fi ori jimi pẹlu ọrọ ti mo fẹ sọ yi, mo tọrọ aforiji lọdọ O l o w o Ajassẹpo lọdọ Ọlọla, lọdọ Saraki, lọdọ mẹkunnu lọdọ Bale ile, Adelebọ ile, Ọdọmọkunrin ati Mundia Ajassẹpo.

Ekeji ni wipe mo ki gbogbo ẹnyin Ọmọ Ajassẹpo patapata, ẹku iṣin ọjọ o. Ọlọrun Ọ b a yio se aranṣe rere fun olukuluku wọn o Amin.

Mo bẹ ẹnyin ẹgbẹ Oṣelu mejeji ni oruko Ọlọrun ati ti Anabi rẹ, ki ẹ jẹki gbogbo wa jijọ panu pọ lati le bẹ Ọlọrun ọba wipe gbogbo iru adanwo buruku ti o ṣẹlẹ si arin ilu wa yi, ki Ọ l ọ r u n masalai ba wa dawọ adanwo na duro bayi Amin. idi ti o mu mi sọ bayi ni wipe tẹlẹ-tẹlẹ ri baba ni ma npa aṣẹ fun Ọmọ, Ẹgbọn asi ma paṣẹ fun aburo, ṣugbọn akoko ti a wa yi ko tun jẹ bẹ mọ, ọrọ na wa di w i p e Ọlọmọ ko mọ ọmọ rẹ mọ, ọrọ na wa di ki a ma sọ ara wa lọwọ ati lẹsẹ, o di wipe ki a ma lọ ran ara ilu miran si ara wa.

Otuu di wipe ki awa ara wa ma dara wa lamu larin ilu, nitorina irufẹ nkan wọnyi ki nṣe nkan ti o le mu ilọsiwaju ilu wa, ki ẹ si tun wa j ọ w ọ ki ẹ jẹ ki gbogbo wa tun bẹ Ọlọrun wipe ki Ọlọrun Ọba ki o ba wa ṣe ilu Ajassẹpo ni Ilu alalubarika gẹgẹ bi ilu Eko yi, ẹ ma ṣe j ẹ k i a di ẹniti yio ma fi ọwọ osi juwe ilu rẹ iwọn ba ni ki ẹ j ẹ k i a fi inu han ẹ n i t i ko ba wa tọn mọ.

E jẹki a jijọ ma tun ilu Ajassẹpo ṣe gẹgẹ bi Ọlọrun tiṣe ba wa pọn ilu na le fun wa ro, ẹ jẹ ki awa na le pọn Ajassẹpo le ju bẹ lọ, ki ẹ ma ṣe jẹki a fi ọwọ arawa fa iya fun ara wa. gẹgẹ bi Aliu Akanbi tiṣe ngbadura si ọdọ Ọlọrun ọba wipe, ki o ba wa ṣe ilu Ajassẹpo ṣe, ki o dara bi ilu Eko yi, ki ẹnyin na ma ba mi gbadura bẹ si ọdọ Ọlọrun Ọba.

Mo bẹ ẹnyin ẹgbẹ Oṣelu mejeji yi, mo fi Alalẹ Ajassẹpo bẹ yin, mo fi Olowu bẹ yin, mo fi Odu Ọja ati Odu Igbo bẹ yin, ki ẹ jẹ ki a jijọ tun ilu Ajassẹpo wa ṣe dara-dara. gbogbo iru rogbodiyan ti o nṣẹlẹ yi, mo fẹ ki ẹ mọ wipe adanwo nla patapata ni. Nitori pe bi o ba jẹ wipe ba yi na ni anba lọ, ti awa ko ba lọ dawọ rẹ duro, irufẹ iwa bayi yio di eyi ti yio fi iya jẹwa lọpọlọpọ, nitori na ki Ọlọrun ma ṣe fi iya jẹwa o Amin.

## Omoba okunrin fe gbeyawo



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Ọmọba ilu Kent, ẹni a gbọ wipe, o ti dagba to ẹniti o le gbe I y a w o, o si jẹ ọmọ bibi inu Prince ti Wales ti o wa s i l ẹ Naijiria ni ọdun 1924, oruko I y a w o ti o fẹ gbe na ni Omidan Kathanne Worsly.

A gbọ wipe Iyawo dagba ju Ọkọ lọ, ọmọ ọdun mẹdọgbọn ni Ọkọ ṣugbọn ọdun mejidilogbọn ni Iyawo rẹ agbalagba ni Ọkọ Iyawo yi si nkọ.

## Petepete T'ana ni Popa

Lati Ọwọ:— DELE ATỌLAGBE.

ỌRỌ RẸ DARA ALUFA H. A. KUṢHORO

Bi mo ba bẹrẹ si sọrọ nisisiyi, wọn a sọpe ọkunrin yi tun de o, ṣugbọn ohun ti oju ba ri ẹnu gbọdọ sọ emi Pẹtẹpẹtẹ Tana ni Popa ọkunrin mẹta.

Alufa Kuṣhoro, ninu ọrọ rẹ ti o jade ninu iwe Irohin "Imọlẹ" ti ọjọ kini oṣu yi, o gba enia ni mọran gidigidi pe ki wọn ma mu ọmọ wọn lọ si ile Kewu, o si tun ṣe alaye pe bi enia ba fẹ kirun wakati marun-o ni ede Laruba (kewu) ni a nlo, otitọ ni anlo ede kewu lati fi kirun. Ṣugbọn bi Alufa Ku ṣ h o r o ba fẹ ṣe nkan na dada, o yẹ ki o lo ọgbọn ati imo rẹ gẹgẹbi o ti jẹpe Akewukewe niṣe lati fi tumọ rẹ Kurani si ede yoruba porogodo ki a si ma kewu ni ede yoruba eyiti iṣe ede awọn Obi wa, ṣe Alufa H. A. Knṣhoro ranti pe ede Heberu ni Bibeli wa tẹlẹ ri, ki awọn Ọjọgbọn Kristẹni to yi si ede yoruba eyiti iṣe ede tiwọn. Ni gbogbo igba ti awọn Kristẹni ba fẹ gbadura ede yoruba ni wọn ma nlo gẹgẹbi o ti ṣe wa ninu Bibeli wọn.

Mọ fẹ sọ fun Alfa Kushoro ati awọn ẹlẹgbẹ re pe lile ti ede Kurani le ni ko jẹki ori awọn ọmọ kekere ya lati kọ kewu rara.a Bi a ba se akiyesi dada, a o ri wipe ọpọlọpọ awọn ọmọ Imale ti wọn nlọ si ile iwe ni wọn ti mọ Bibeli ka dada nitoripe ede yoruba to ye w ọ n ni wọn n fi kọ. Ṣ u g b ọ n o yẹ ki Alufa uṣhoro mọ daju pe kosi ede ti Ọlọrun ko gbọ, yala Ibo, Hausa tabi Yoruba ko si eyiti ko ṣe kirun tabi gbadura ninu wọn.

KOITI PARI

POOLS! POOLS!! POOLS!!!

## Awon Akiyesi Pataki

Ẹjọwọ eyi ni lati le kede fun gbogbo awọn onibara iwe Orire wa ni ilu gbogbo pe, orire (T i c k e ts) ti Gentral Pocls ti jade fun tita, ati rira nisisiyi.

Njẹ iwọ ti ri ra ninu iwe orire na ri bi? Nisisiyi osi nbẹ yika ni gbogbo ilu, jọwọ, tete ra tirẹ loni.

Bẹni asi nfẹ awọn asoju ati agbọn alagbata ni ilu gbogbo bi Eko Ghana, J o s, Nguru, Warri, Sapẹlẹ, ati bẹbẹ lọ pẹlu. Jọwọ tete kọ Iwe fun Ticket, iwe orire na loni si:-

THE CENTRAL POOLS SYNDICATES
P. O. BOX 575, IBADAN, NIGERIA.

TO LET

A Room & A Varandah is Vacant, Apply to:-
16, Bamgbose Street,
Lagos Nigeria,

# Ajegboro dagba Nki Nyin O!

## ẸYIN ỌMỌ ILE ẸKỌ, Ẹ MURA SI IWE YIN. ẸFI AIYE JIJẸ SILE

### O BẸRE LATI ỌSẸ TOKOJA

Emi ti mo ba yin sọrọ yi, emi ki ṣe ẹbi rẹ tabi ẹgbọn tabi aburo rẹ, bi o ba si di enia pataki lẹhin ọla, ogun rẹ ko le kan mi. bi o ti ẹ mọ mi o ko le tọ rọ owo lọwọ rẹ ki o fun mi, ṣugbọn gẹgẹbi mo ṣe jẹ ọkan ninu awọn Aṣoju Irohin-Imọlẹ, mi ko gbọdọ ri on ti ko dara kini o dara fun ẹnyin Ọkawe Irohin Imọlẹ tabi ki ri on dudu ki pe ni funfun lai ki ṣe pe o jẹ funfun. Iṣẹ mi ni pe ki ri ibi okunkun ki si tan imọlẹ sibẹ tabi ki ri ohun ti ko da ki yara sọ fun ẹnyin Ọkawe Irohin-Imọlẹ nitorina ni mo ri pe iwa aibikita o kun ode nisisiyi fun awọn ọmọ ile ẹkọ ati awọn ti wọn kọsẹ nipa aiye jijẹ. mo si nero wipe iru iwa bayi ko fun ilẹ Naijiria ni idagbasoke, ko tun yẹ ilẹ ti o ti gba O m i n i r a ki awọn ọmọde wọn ma wu irufẹ iwa bẹ, ni mo ṣe ki gbe pe aiye jijẹ ko dara fun ẹnyin ọmọ ile ẹkọ tabi ẹnyin ti o kọsẹ. Ṣugbọn mo nero wipe boya ti mo ba ki gbe bayi Ọlọrun le jẹki ẹ ronu piwada ki ẹ si mura si ẹkọ yin.

**Lati Owo:- LATIFU BABALOLA**

Iwọ ọmọ J. J. ti ẹ ro ri rẹ wo pe ẹniti o bawa sọrọ bi ọmọ iya wa yi ki iṣe ebi wa tabi bẹ si ni kiṣe ẹgbọn wa ṣugbọn o fẹ ki igbesi aiye wa le dara lẹhinọla.

Nitorina mo bẹ yin ẹ mura si ẹkọ yin, asiko lọ ko ko duro de ẹnikan. Naijiria ti di Om'nira o si yẹ ki ẹnyin Ọmọ ile iwe ma tẹ si waju lati ma mọ ohun ti o nlọ ni ilẹ Naijiria. ki ẹnyin sa tọ di enia pataki lẹhinọla, Nitori boya iwọ ti o ṣe ọmọ jaiye jaiye ni yio di Olotu Naijiria lẹnin ọla nitori awọn Agbalagba lo ma powe Pe "Igba ki tọ lọ bi orere, aiye ki tọ lọ bi ọpa Ibọn" itumọ rẹ ni pe aiye yi ni, igba kan nbọ ti gbogbo awọn Alakoso wa yo lọ, ti yio si tun ku ẹnyin ọmọde isiyi nitorina iwọ ko ti mọ boya enu tabi iwọ ni yio Olotu Naijiria lọla, nitorina mo bẹ yin lọpọlọpọ ki ẹ mura si iwe yin iwọ ti o si nkọsẹ ki o mura si, ẹnyin Ọmọde ẹ matẹ siwaju lati ma mọ ohun ti ọ tọ si ilu yatọ si pe ki ẹ ma ṣe ọmọ jaiye-jaiye kiri ki ẹ fi oju si ẹkọ yin ki ẹnyin na le di Ọlọla Naijiria lẹhin ọla.

Mo bẹ yin ni orukọ Ọlọrun Ọba to ni aiye ti o ni Ọrun, ki ẹ jawọ ninu aiye jijẹ. Melo ni iwọ ri ninu awọn ti wọn ti kanju jaiye ti igbẹhin wọn dara. E sọ lo laiye ẹ maṣe kanju jaiye, ẹ ma ṣe kanju ju asiko Ọlọrun lọ iwa rere lo yẹ ki ama wu. Ki ẹ fi aiye jijẹ silẹ ti ẹ ba fẹ idagbasoke Naijiria lẹhin ọla. Iwọ ti o mọ yẹyẹ ṣe, ti o ba ti ka ọrọ mi lọwọ yẹyẹ ni ki o ma fi mi ṣe maṣe lọ ronu piwada ki o yara lọ jawọ ninu iwa aibikita, tani o ma mu, ti o wu kakiri, ikan ti yio mu ọ wa ni ipakọ rẹ, ati pe ṣe iranti pe o bọ wa dagba ti ẹ san yio ma ke lori rẹ, nitorina ẹ jẹ ka ma gbọ rọ si awọn Obi wa lenu, ti o ko ba ri ẹni sọ fun ẹ, o yẹ ki iwọ na lọ rori rẹ wo pe agbalagba loda lọ yen. tabi bi o ti ṣe wa ni ọdun to koja ni o ro pe o wa lọdun yi, o jẹ ya lọ danu si ode ki o si fi oju si iwe tabi iṣẹ rẹ.

Ọmọ ti ko to ẹ nsare si iwe rẹ, iyawo ni Alakọri rẹ kiri, tabi ki o lọ si ile ijo, ti wọn sọ fun ẹ titi ti o ko gbọ igbẹhin ni o dun oloku ada si, bi o ba ni on lọ si ile ẹkọ, Marina ni yio gba lọ, tabi ki o lọ sile Kudiratu o jẹ ya tete lọ jawọ ninu rẹ nisisiyi. Odi ile iwe mẹta ti wọn ti yọ ẹ kuro o ko tori ri rẹ ronu piwada, o ṣe oṣi bi ẹran aṣẹwo Alakori obinrin ti ko si ni agbari ko jẹki o le joko sile ẹkọ mọ.

Abọro la sọ tun ọmọ luwabi ti o ba de inu rẹ yio di odidi, Nitorina ẹniti o ba wun ki o gdọ, ki o si gba ti o ba si wun ki o gbọ ki o ma gba. Ṣungbọn mo mọ daju wipe lagbara Ọlọrun o bọ wa kaba mọ rẹ.

Mo bẹ ẹnyin ti ẹ fi oju si iwe yin ati ẹnyin ti ẹ nkọṣẹ ti ẹ si fi oju si, ki ẹ mura si, bi ẹ ti ṣe ni ki ẹ maṣe ẹ ma ṣe tẹle awọn Oniranu ti wọn pe ara wọn ni ọmọ Jaiye-jaiye, ẹ ma kawe yin nigbagbogbo ẹ m wo ti wọn, bi o ba titi ẹnyin na bọ wa di Oga.

Njẹ emi ọmọ babalola nrele, emi ni asọrọ bi ẹni mọ tele, origa ti gbe Olẹ ko si, Oriburuku ki ṣe temi Ọmọ Akin nrele Odigba Odigboṣe o.

**For all your Printing**

**Reguirements**

Invitations, Programmes Hand bills,
Pamphlets, Advertising
Material and all
Commercial Jobbing

Send your Jobs to:-

MODUPE PRINTING PRESS

16, Bamgbose Street, Lagos. Phone: 21985

**Where Quality Print, costs less.**

# Asiwaju awon Oselu Saro Nki Omo Gesi



Eniti o mura gẹgẹbi Jagun-jagun ti o si bẹrẹ ni ọkan ninu awọn Ọmọba ọk u n r i u ti nwọn npe ni Duke of Kent nigbati o gunlẹ ninu ọkọ ofurufu silu Saro, ẹniti o si wọ subys funfun ti o de fila Awo ni Milton Margai.

**E ma ka iwe Irohin Imole fun Irohin a ti oro isiti**

# ISE KI PANI, AYO NI PA ENIA

## O BERE LATI OSE TOKOJA

Owaro r• bere lọwọ ọmọde yi pe jọwọ ọmọdekunrin "bawo ni ile iku se jina to si ibi yi?" ọmode si tọka si ọkankan pe ile ıku ni iwọ nwo lọkan ni". Inu ọkunrin yi dun nigbati ori Ile yi, osi sare lati tete de ibẹ.

## ỌKUNRIN YI RI IKU; O SI WỌ ILE RẸ LỌ:

Bi o ti ku diẹ ti o ma de ile iku ni ori ti Iku jade pẹlu kumọ nla kan ni ọwọrẹ. Bi o si ti ri, bẹni ọkunrin yi sare si lati di mu ki o si sọ gbogbo ohun ti on bawa fun. Ṣngbọn iku ni ki omase di on mu rara.

Nıgbati ode ọdọ iku, iku mu wọ inu ile rẹ lọ Iwọ ọrẹ mi ile iku bami lẹru pupọ. Ẹnyin Onikawe Irohin

**Lati Owo:- Simeon Adegoke Faloki**

mọlẹ, mo bẹ nyin ẹma se huwa buburu siile aiye, ki ẹ ma huwa rere si ọmọ araiye. Iwa ika ko pe rara ati pe g b o[g b o rẹ wa ni ode Ọrun, ranti pe iwọ ko ni oda ra rẹ si ile aiye? ranti be asiko kan wa ti iwọ ko mọ hun kan rara. Ranti pe afi ọgbọn ori re fun o ki iwọ e fi se rere fun ọmọnikeji rẹ ni, ki iwọ le ba fi ọgbọn na mọ Olọẹun ti oda ọ. Iwọ tı o ni owo ranti pe afi owo yi fun ọ ki ole bo le fun igbeleke orukọ Ọlọrun, Ako fi fun ọ ki ole ba mase fari ki o si rantibe ıpo ti owa loni ole gbe ọ kuro ni Ọla. ki o si rantipe boya ni ọla ilẹ le sai mọ ba ọ.

Bakanua ni iwọ alagbara, mofẹ kı omọ pẹ ako fun o ni agbara yı lati fi ba tí ọmọnıkejı rẹ jẹ. Rant ipe afi agbara yẹn fun o ki ole lo fun igbeleke orukọ Ọlọrun kı osi mọ pe ale gba lọwọ rẹ nigbakigba.

Gẹgẹ bi mo ti se nsọ lẹkan, ẹnyin Onikawe yi mo sọ yın pe, Ọkunrin yı wọ ile iku nıgbati osi de ibẹ i k u kọkọ mu rin kiri inu ;le na. Ohun iyalẹnu meje pataki lowa ni ile ıku, ti aba si sọ pe a o ma sọ gbogbo rẹ ni ọkọkan yio gba wa lasiko pupọ. Lakọkọ ọkunrin a rẹwa kan wa ni ile iku asi fi ẹwọn i r i n de ọkunrin yi mọlẹ ni Igun ile iku ni, lẹhin eyi ni mo ri ọwọ kan ti nwa lati oke ti osi bẹrẹ sı na ọkunrin ni ẹgba kọkan, ti ọkunrin yi si nje irora ni gbogbo ọjọ aiye rẹ Ọkunrin ti otẹle iku yi bere oni. "Jọwọ ma sai sọ fun mi, iru ohun tı ọkunrin yi se tobayi?" Iku daa lohun o n i "Nigbati ọkunrit yi wa ni aiye afi ọgbọn, owo, agbara, ati Ọla tẹ lọrun, sugbọn kaka ti iba fi fi gbogbo nkan yi mọ awọn ọmọ aiye ati Ọlọrun, obẹrẹ sı lo ipo re bi oti wu, osi ti gbagbe pe ni ọjọ kan sa ẹni tı o fi on sile aiye, yio mu on kuro nibẹ. Ose bi o ti wu, sugbọn Ọlọrun dakẹ onwo, boya yio ronupiwada ki asi dariji, ṣugbọn ko se bẹ rara, nigbatı odi ọjọ kan Ẹlẹda pe mi osi sọ fun pe ki n l ọ mu ọkunrin yi ni aiye, mo se bi Ẹlẹda ti se wı mu si mu wa sı ọdọ mi nibiu oti nje ıya ohun ti oti se ni ile aiye. Bẹna si ni ẹnıkọkan awọn ti o ri iwọ n yi se de ıbiyi.

IYO KU DI ỌSẸ TO MBỌ


THE RADIO ACTIVE REMEDY

IN WEAKNESS
DEBILITY

ANÆMIA

use
Deschiens'
Syrup of Hæmoglobin

Regenerator of the blood prescribed by the most important Physicians. Your chemist has it

INSIST ON THE NAME OF DESCHIENS. PARIS (France)

Sole Distributors for Nigeria:-
WATERLOO MEDICINE STORES
Continental Medicine Specialists,
8, Palm Church Street, P. O. Box 333,
Lagos Nigeria. Phone: 22375



# KERE O, Akiyesi Pataki

**Antoin Tablets! Antoin Tablets!!**

Enyin Abiyamọ lọkunrın ati lobinrin. Mo ba yin yọ E ku afojuba E g b o g ı pataki ti aṣe iwadi rẹ lati ọwọ awọn Ọjọgbọn Onişegun (Specialists.) Ilu Oyinbo.

Fun awọn ajakalẹ Arun wọnyi:—

IGBONA:- Eyi yi jẹ Arun tı o ṣọpọ ni ode isisinyin papa ni arin awọn Ọmọde ati Agbalagba.
ORIFIFO. TULU. LUKULUKU. OTUTU IGBA AYA. ARA RIRO, atı OTUTU ỌRẸRẸN pẹlu AKOKORO Jọwọ danwo Ajẹbidan ni ogun yi. Irohin ko tı Afojuba

Bereiwe ti ẹ o fi lo lọwọ ẹniti o ba ta E g b o g i na fun yin. Odaju hanwun. Ẹ o ri işẹ rẹ lẹhin isẹju mẹdogun ti ẹ lo. Bere lọwọ awọn onişegun adugbo rẹ.

*Distributors*
HASSAN COMMERCIAL MEDICINE STORES
26, Bishop Street Phone: 23745

LAGOS



EYI NI TI EMI...

THREE THREE'S

TRIKOLA!



TRIKOLA
333

SWORD BRAND

O BERE LATI OJU EWE KINI

la wakati meji lori iduro mbiti nwon gbe mbi lere ọrọ ni ẹdọ awọn Ọlọpa Inu ni Ọbalende.

Awọn Ọlọpa bere lọwọ Alufa na wipe, o ṣe ti nwọn ko fi posi sinku ọmọ na ti o fi jẹ w i p e, aṣọ ni nwọn we mọ lara.

## Awon Awujo egbe Onigbajamo se pade ni Ibadan

IBADAN:- Awọn ẹgbẹ Onigbajamọ (Barbers) ṣe ipade alariurin kan laipẹ yi nigboro ilu Ibadan, ninu ile ẹgbẹ ni Oke Mapo· Ṣeranwo gbe boroki loke Mapo ni dede agogo marun abọ ọjọ 9th oṣu yi, enia dabi omi.

Ijọba fi awọn Ọlọpa meji da apejọ na lọla ki ipade na to pari, lati moju to wọn ki o ma ba si ija tabi ede koyede. Ohun ti o fa ipade na wa ni wipe lati jẹ abọ fun awọn ọmọ ẹgbẹ nipa dide ti iwe aṣẹ titun de fun awọn ọmọ ẹgbẹ na, eyiti a npe ni Registraion.

Ọgbẹni Alabi lo fi adura si ipade na, o ṣe alaye bi iṣẹ gbajamọ ti niyi to ati iṣẹ ribiribi ti akọwe agba ṣe eyi'ni Ọgbẹni Tijani Oduyebọ, ti o ti mba iṣẹ na bọwa lati ọpọlọpọ ọdun ṣẹhin. Nwọn si ṣọrọ iwuri nipa ẹgbẹ yi.

Lẹhin eyi ni Ọgbẹni Tijani Oduyebo wa ka iwe aṣẹ na fun gbogbo ọmọ ẹgbẹ, inu awọn ẹgbẹ na si dun gidigidi si aṣeyọri iṣẹ na. Ki ipade na to wa si i p a r i, gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ na si fi ohun kan fi aṣẹ si irun gige nigboro ilu Ibadan, ati yika ibi gbogbo ni ipinlẹ Iwọ Orun bayi:- Oyinbo, Sile meje abọ Ọmọ titun, Sile marun, lati gerun ninu ile. Ṣile meji abọ, Ọga ilo iṣẹ 5/ Fifari korodo 1/ Gigerun agba 1/6 Irun Ọmọde 1/

Diẹ ninu awọn gbajumọ ti o wa sibẹ ni Ọ g b ẹ n i Tijani Oduyebọ' S· Olowooṣke, Olori, Alabi, igbakeji, R. Ẹniọla Balogun Ayinde Ọlọrunnisọla, I s i o y e, P. Egenewe, R. O. Adeẹkọ Adegbitẹ, K. Marindọti, J. A. Adesanya, M. A. Sam Akinyode.

## Ewa wo Ere Aladun

ARI MA LE LỌ, AWO PADA SẸHIN.

### EGBE ARIKEWUYO Omo ilu Ilala (Lagos branch).

Awa ẹgbẹ ti orukọ rẹ wa ni oke iwe yi fi tayọtayọ pe ẹnikẹni lati wa wo ere MỌLIKI GBUGBU E L E RE EGUN, ere ti yio ṣe yi jẹ akọkọ ti kọ ti ṣe iru rẹ ri ni Eko nibi yi.

A pe ẹnikeni lati wa fi tayọtayọ wa wo ere na ni alẹ ọjọ aisun ọdun Ileya ti ṣe ọjọ merinlelogun oṣu karun ọdun yi. (24:5:61)

Ibiti a o ti ṣe ere na ni yi:- NO 87, LEWIS STREET LAGOS. Lọna Ọbalende ni Eko. Ere na yio bẹrẹ ni dede agogo mejọ alẹ titi di agogo mẹrin oru moju ọjọ keji (From 8p.m. - 4a. m.) Irohin ko to afojuba ni ere na, ẹniti o ba ri lo le sọ.

Owo Iwọle bẹrẹ lati ṣile marun, ati Ṣile Mẹta. (3/- and 5/- Fiat). Ere na yio ju iye ti ẹ fi wọle lọ. A ki gbogbo awọn Ọdọmọkunrin pẹlu Ọdọmọbinrin ati gbogbo awọn Agbalagba, Oluwa jẹki ọjọ na bawa l a i y e pẹlu Alafia ara. Amin Ẹ ku ipalẹmọ Ọdun Ileya na.

Eyi ni Ibiti ẹ o ti ma ri Tikẹti (tickets) wa ra:-

1. D. Babalọla ni No. Glover Street, Lagos.
2. Yakubu Alabi No. 6 Inasa Court, Lagos.
3. Jimọh Ayanda & Brothers, 60, L. E. D. B. S h o p Idumagbo Avenue, Lagos.
4. Y. K. Alabi No. 1. Reclamation RD. Lagos Nigeria

Printed and Published by MODUPE PRINTING PRESS 18 Bamgbose Street Lagos Phone: 21983. Olotu: E. A. Aderoji 51, Tejuosho Street Suru-lere, YABA.

## IDIJE IDIJE IDIJE

A fi eyi ṣe ikede fun gbogbo Ọkawe Irohin Imọlẹ Jake-Jado Agbaiye ati awọn Ọmọ Karọ-o-jire pe anfẹ:- Ẹniti o ba le ba wa fi awọn ọrọ si ibiti a fa i l a kekere si, ati pe awọn kan tun wa ninu rẹ ti a ko to dada-anfẹ ẹniti o ba le ba wa to si ipo rẹ dara-dara ti yio si ni itumọ.

Ẹnikẹni ti o ba si bori ninu gbogbo rẹ yio gba Ẹbun pọnun-kan ṣile-kan (£1 : 1/-).

ỌRỌ NA NI WỌNYI

Ọrọ yi jẹ orukọ awọn enia pataki nilẹ Yoruba ti nwọn si ti di ologbe:-

| | |
|---|---|
| 1. __ __ A __ Y __ __. | 6. M __ __ E __ __. |
| 2. O __ __ N __ __. | 7. __ A __ __ O. |
| 3. __ __ U __ __ W __. | 8. O __ O __ ... __ I· |
| 4. O __ __ P __ __ __. | 9. O __ __ N–O __ __. |
| 5· __ B __ __ M __ –N. | 10. A . . ... T __ __ __ |

Orukọ yi jẹ orukọ awọn Ọba nilẹ Yoruba

1. O __ __ N __ __
2. E ... __ J __ __ B ...
3. A __ __ W __
4. O __ __ D __
5. A __ __ __ __ U __ __

Tun awọn ọrọ wọnyi to dara-dara:-

1. GOOINANS __ __ __ __ __ __ __ __
2. AIJNIDE __ __ __ __ __ __ __ ..
3. GABRNOI __ __ __ __ __ __ __
4. ASLIHE ... __ __ __ __ __
5. OINMMION __ ... ... __ __ __ ... __

Awọn orukọ wọnyi jẹ orukọ Ilu ni ilẹ Naijiria:

1. __ G __ O __ ... __
2. I ... B __ __ A ... O
3. K __ __ A ... C __ __ N
4. A __ ... T ... G __ O
5. ... A __ ... B __ R.

AKIYESI:— IDIJE yi yio pari ni gbigba n ọjọ keta oṣu keje ọdun yi (3 : 7 : 61) kọ ọrọ tirẹ ki o han rekete, ẹniti tirẹ ko ba han, a o fa ya ni, ki ẹ si mọ d a j u wipe, ko si ojoro ninu Idije na, ẹniti o ba ṣe gbogbo rẹ, ti o sii gba a, ni a o fun ni Ẹbun pọnun-kan Ṣile-kan (£1 : 1/-) Postal order ranṣẹ si.

Fi Stamp Tọrọ ranṣẹ fun gbigbe pọnun-kan Ṣile-kan ti o ba jọ ranṣẹ si ọ. Ge ibiti Idije yi gbe wa, ki o si fi ranṣẹ pẹlu Stamp Tọrọ tirẹ. Ẹnikẹni ti ko ba ge Idije tirẹ ranṣẹ, ti ko ba si fi Stamp Tọrọ ranṣẹ pẹlu, ti o ba jẹ a ko ni fi ranṣẹ si onitọhun, a ko si ni fun ni Stamp rẹ pada mọ.

Orukọ ............................................

Ibugbe ............................................

............................................

Iṣe ............................................

Ọjọ Ori ............................................

Fi Idije tirẹ ranṣẹ si:—

OLOTU IROHIN IMOLE
16 BAMGBOSE STREET LAGOS.